# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 568 WEDNESDAY, APRIL 1, 1964 (2D)


## Abayọri Eto Ikania Fẹ Di Ọrọ Kotu!

ONITSHA:— Gbogbo enia lo palọlọ bi awọn ti pọto nigbati Ọgbẹni V. C. Ikeotuon , ti iṣe akọwe ẹgbẹ awọn Ibo ni Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria nigbati o nba awọn enia sọrọ ninu Ile Rex Sinima Onitsha lori abayọri eto ikania ati awọn ohun ti o ti bẹrẹsi ṣẹlẹ lati igbana ati ohun ti awọn ọmọ ẹgbẹ Ibo npete lati ṣe lori eto na.

Ọgbẹni Ikesotu ny, ti iṣe ọkan ninu awọn ọmọ Ile-Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria tun sọ fun gbogbo enia wipe, ohun kanṣoṣo ti o le yanju ariyanjiyan ati awuyẹwuyẹ ti o wa lori abayọri eto ikania yi ni 'wipe, ki Apapọ Ijọba Naijiria o yan Igbimọ kan ti ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan lati tun awọn enia orilẹ-ede yi ka.

Ọgbẹni Ikeotuony tun bu ẹnu atẹ lu iwa iya ara ẹni sọtọ eyiti osọ wipe awọn enia Ipinlẹ Ariwa nhu.

Otun ṣe alaye pe ko si ilu kan ti ole ba v j v( ) h ya enia Ipinlẹ kan si alejo larin ilu kanna.

Ki ipade na to pari, awọn ọmọ ẹgbẹ na bu ẹnu atẹ lu Alhaji Abubakar Tafawa Balewa fun ọna ti o gba mu eto ikania yi, nwọn si se ipinnu wipe, "ohunkohun ti oba sẹlẹ lẹhin abayọri eto ikania yi. Alhaji na lo da a silẹ."

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ni gbọhin-gbọhin ni awọn duro lẹhin Dokita Michael Okpara, awọn si ti se tan lati se oniruru iranl wo fun un lori iduro rẹ.

Agbọ wipe, ẹgba a (2,000) awọn Ibo ni Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti le kuro ni Ipinlẹ wọn, nwọn ti tun le ọpọlọpọ jade ninu ile wọn nitori ọrọ eto ikania yi na,

# FANI–KAYỌDE TU IGBIMỌ IJỌBA MUSHIN KA

IBADAN:— Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti da Igbimọ Afunṣọ Ijọba Muṣhin duro lati ma a ṣe ipade tabi lati tun maa ṣiṣẹ wọn lọ gẹgẹ bi alamojuto eto Ijọba Muṣhin ati agbegbe rẹ, bẹni iwe na tun ṣe alaye pe, "Awọn alaṣẹ Igbimọ na kọ gbọdọ ṣe ipaade titi ti Ijọba yio fi fun wọn ni aṣẹ".



Oloye FANI-KAYỌDE

Oloye Fani-Kayọde, igbakeji Alakoso Ijọba ati Minista Alamojuto eto Iijọba Ibile ni o kọ iwe idaduro si awon Igbimo Afunsọ Ijọba Mnshin na.

Irohin ti ye wa lati Ile iṣẹ Minista na lana wipe, Oludamọran Ijọba Agbegbe Abẹo uta ni vio maa ba eto iṣẹ Ijoba Mushin lọ titi Ijọba yio fi ṣi lọwọ iṣẹ, ti yio maa ṣe amojuto ilu Mushin.

Oniwe irohin wa kan fi ye wa wipe, nitoripe awọn ọmọ Ile Igbimọ Ijọba Afunṣọ Mushin ko ti le kede lori ẹrọ R e d i o fun gbogbo araiye gbọ wipe, awọn ti kuro ninu ẹgbẹ oṣelu ti awọn nṣe, awọn si ti darapọ mọ ẹgbẹ oṣelu titun ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ, eyi ni ẹgbẹ Dẹmọ (N. N. D. P.) ni o jẹki Oloye Fani-Kayọde o tu Ile Igbimọ Ijọba Mushin ka.

A gbọ wipe ṣẹ ti Ibadan wa si Muṣhin lati ọdọ olori ẹgbẹ N.N.D.P Dẹmọ pe, ki awọn enia na o tete sọ fun gbogbo aiye pe ẹgbẹ Dẹmọ ni awọn nṣe ṣugbọn nigbati aṣẹ na de, awọn enia na kọ eti ikun si iwe na, nwọn ko si sọrọ

Lẹhin ti awọn enia na reti pe awọn fẹrẹ gbọ, ti nwon ko si gbo nkankan ni iwe ba jade ninu Ilẹ iṣẹ Minista Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ pe, ki nwon tu Igbimọ Ijọba Muṣhin ka.

Oniwe irohin wa Ejon'gbo ro wa Oloye Adeniran Ogunsanya ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ninu Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria ti i s i tun ṣe alaga Igbimọ Ijọba Muṣhin lo si ile lana lati lọ gbọ ọrọ lẹnu rẹ, ṣugbọn ko baa nile.

Sugbọn Agbọrosọ awọn ọmọ ile Igbimọ Ijọba Mushin ti oniwe irohin wa ba pade lana se alaye wipe, awọn enia mejila ni awọn wa ninu Igbimọ na.

Ninu awọn mejila yi, enia mẹwa ninu awọn ni ko faramọ ẹgbẹ Dẹmọ, enia meji yoku si faramọ.

Otun se alaye wipe, awon ti se iwe kan ti gbogbo awọn ti fi ọwọ si, pe ki awọn fi mu ẹnu-aiye kuro ki awon si fi iwe ranse pe, "Ẹgbẹ Dẹmọ ni gbogbo awon nse" bi o tilẹ jẹ wipe awọn ki ise ẹgbẹ Dẹmọ.

Oni, nigbati awọn ṣe eto na tan, ti awọn si fẹ fi iwe na ranṣẹ ni awọn yoku ba tako eto na, Agbọrọsọ na ni gbogbo awon Igbimọ Ijoba Ibilẹ ti nwon nso pe, "awon di ẹgbe Dẹmọ" o ni nwon nfi ẹnu jẹ ẹgbẹ Dẹmọ ni, nwon ki iṣe ẹgbẹ Dẹmọ ninu ọkan wọn, ibo atundi ni awon enia na si nduro de ni Ipinle yi bayi.

Onirohin wa kan fi ye wa pe, nwọn ti le gbogbo awọn obinrin ọloja kuro ni ọja Ararọmi, nwọn si ti wo gbogbo iṣọ ti awọn obinrin na gbe nta ọja.

A gbo wipe, awọn kan ni nu awọn ti nwon ni ọja Ararọmi ti Ijọba Mushin wo ti pe akowe Ijoba Mushin ati awon Kansilo meji ni ejo si Kotu bayi.

Bi nwon ba ti pari oro na si, ẹ o maa gbo o.

### ORỌ ỌJA

Ninu iwe keji ti Oloye Fani-Kayọde kọ si akọwe Ijọba Ibile Mushin, o ṣe alaye sinu iwe na wipe, nwọn ko gbọdọ le awọn enia kuro ninu ọja Ararọmi lọ si ọja tuntun titi ti Minista Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ yio fi risi ọrọ na.

O tun ṣe alaye sinu iwe na wipe, ki o mu awọn obinrin mẹwa wa si Ibadan ninu awọn Aṣoju obinrin oloja Ararọmi ni ọjọ Ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu ti o koja yi ni deede agogo mẹwa si mejila ọjọ na ki awọn si jijo jiroro lori ọrọ na, ṣugbon akọwe na ko lo si Ibadan ko si jiṣẹ fun awọn obinrin ọlọja na.


"DEFACTO"



# IWE SI OLOTU

## Mo gba fun Iwe Irohin Imọlẹ

Ẹ jọwọ ẹ gba mi ni aye lati dupẹ ti o tobi lọdọ awọn Olotu Irohin Imọlẹ Ọgbẹni Ejongboro ati awọn to nṣiṣẹ ninu Iwe Irohin Imọlẹ fun whala ati akitiyan ti a fi nri iwe Irohin Imọlẹ ka lojoju-mọ ti ko si npẹ ki o to ma jade.

Bi enia ba ṣe ni lore ti a ko si ni owo lọwọ ti a le fun oluwarẹ, ti ao ni nkan nla ti a le fun gẹgẹbi ẹbun, nkan pataki to yẹ ki a ṣe nipe ki a lu ni ọgọ ẹnu pe, o ṣe pupọ o.

Nigbai mo ka iwe nyin ti ọsẹ tokọja o ya mi lẹnu gan ni pe aja mẹfa yege nwọn tun gba we ẹri iṣẹ ọlọpa Gbogbo wa ni ko gba ọrọ na gbọ, a fi bi a ti wo iwe irohin ni ede Gẹesi ni a to mọ pe kiṣe asọdun rara

Ṣugbọn nibo ni ẹ ti ma ri awọn ọrọ ti ole ma ya lẹnu? Eyiti ko ye wa ni bẹ ni pe ẹ mọ ojulowo Yoruba bẹna ni ẹ mọ rọ ti o ba ọrọ mu.

Ẹku iṣẹ o Ajinde ara yio mọ jẹ ko ni rẹ nyin lailai.

Emi ni
LIADI ADIO
Akurẹ

mi to wa ni ilu Ijomu-Oro lori ọrọ oye ti nwọn ndun mọ ara wọn lọwọ, mo fẹ ki wọn na suru-si nitoripe suru ni o le tun nkan ṣe ni aiye wa ode oni.

Mo fi Ọlọrun bẹ awọn agbagba to wa ni Ijọmu-Oro pe ki wọn ba wa mu oju to ọrọ na ki o to di isu ata yan-yan ki ẹ pe ọtun ati osi ki ẹ pari rẹ fun wọn.

Ẹnyin agbagba ati gbajumọ ati awọn bi Bello Aro Alufa Bunlẹmọ ati awọn yio ku, a dupẹ lọwọ wọn fun siṣọ ti nwọn so oj abẹ niko ni ọjọ Aiku ti ṣe ọjọ kẹja oṣu kẹta ninu ọdun yi. lori ki ọtẹ ti o wa nilẹ yi le pari Inu wa dun si ọrọ na ti o pari nitorina ẹniti inu ba nbi a fi Ọlọrun bẹ ko fi ọwọ wọ inu o. Ẹ jẹki a wa ọna ti anfani wa ko ni mọ fi lọ si ilu Ilọrin mọ ẹ mọ fi ọtẹ silẹ ki ẹ mo pa lapalapa mọ.

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi

Emi ni
R. A. ỌLADIPỌ
Ijọmu-Oro

## Esi Ọrọ Afọlayan

Ẹ dakun ẹ gba mi laye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ lati dahun si ọrọ Ọgbẹni Afọlayan ti o bere ninu iwe nyin ti ọjọ keje osu kẹta ninu ọdun yi ti o bere wipe kini o fa ti nwọn fi nkọ Aka si Ọffa nile ati loko pelu.

Idahun temi nipe, ni aiye atijọ ko si panu ni agbegbe Ọffa rara lati fi kọ ile koriko ni nwọn nlo nigbana ni nwọn mọ fi kọ ile ni ni arin ilu ati oko pelu.

Idi pataki ti nwọn nfi nlo Aka nipe, bi ile yio jo ko mọ ba ran arawọn. Ọgbọn lo mu wọn mọ fi aka kọle nigbana.

Sugbọn ni asiko yi gbogbo ile ti di oni panu ẹnikẹni ni ole mọ ko nkan oko re sinu ile ni aiye ti awa yi.

Inu mi dun si ibere yi Ọlọrun yio wa pẹlu rẹ o Ọgbẹni Afọlayan

Mo dupẹ pupọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi, ajinde ara lo mọ jẹ o

Emi ni,
ISHỌLA
Okeya

## Ibadan eyi ti Pọju

Olotu ẹ gba mi ni aye lati sọ ọrọ mi yi fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun paapa Ijọba Ibilẹ Ibadan pe ki wọn ye le awọn enia mu nitori owo ori mọ, enia ko le sun tanran ninu ile rẹ, bi o ba fẹ wo ita o di ijaiya.

Mo fi Ọlọrun Ijọba Ibilẹ Ibadan ki nwọn ni suru si ọrọ na, ẹ mọ ṣe ni iyọ ko dun ọbẹ awa nkan ara mo ewe ẹ fi suru si ọrọ wa.

Ati awọn ọmọ ile-ẹkọ ati awọn ti kọ nise lọwọ ni nwọn nle mu kakiri Igboro ilu, bawo ni ọmọ ile-ẹkọ ti se le san owo ori nigbati ojẹ pe awọn nbọ on na ni, ki awọn obi ti o san owo ile-ẹkọ ki nwọn ra iwe ati aṣọ fun ọmọ wọn tan, ki nwọn tun mọ da owo-ori ẹ fi ero si.

Tabi ẹniti nwa isẹ ẹniti okoṣẹ tan ti ko ti ri owo ra irin-isẹ, ko ti ri onjẹ oojọ rẹ jẹ ni asiko depo ti yio fi rio wọ ori, mofi Ọlọrun bẹ nyin ẹsanu awọn ọdọ wa

Emi ni
LASISI
Ibadan

## Ọrọ Oye ti pari

Jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ ti nkọ wa ni ọgbọn ati oye lati sọ ọrọ mi yi fun awọn enia


## Akiyesi Pataki

A nfẹ Aṣoju ni awọn ilu wọnyi, Otta Abẹokuta, Ibadan, Iludun, Olodo, Agbọwa,-Iko si Ikorodu, Ọyọ, Awẹ, Ilesha, Ẹde, Ikirun, Iwo Shaki Iṣẹyin, Tede, Oke Amu, Iganna, Omu-Aran Ilorin Ajaṣẹ-Ipo, Iffọ Abalabi, Idọgọ.

Akowe si
Circulation Manager.
Gbamgbose Street,
Lagos.



AH ! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid-Ul-Kabir Dance**

AT

**FORSTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Offices Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.



BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yato patapata si awọn

**RICHALET** Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyen ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yen rara tab ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yen a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apọ ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pelu

Bere egbogi aẹjbina Royal yi ni ṣọbu wọnyi:—
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Fai)
(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street, Yaba

# Ole ti O fọ Ile Onile Wẹwọn Ọdun Mẹrin

IBADAN:- Oju gba gbogbo ero ti o wa woran nile ẹjọ kekere kan ni ilu Ibadan ti nigbati awọn Ọlọpa bere si ka ẹsun ole jija fun ọdọmọde kan Solomon Alao ti iṣe ọmọ ọdun mejidinlogun niwaju A d a j ọ Ọgbẹni Ọlayinka Odumosu.

Nṣe ni gbogbo ero ke ha! ha!! ha!!! bi awọn ọlọpa ti nsọ fun A d a j ọ wipe ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu ti o kọja yi ni Alao lọ fọ ile kan ti o wa ni Opopo Ring Road ti Osunmi ni ilu Ibadan.

Ọlọpa na tun ṣe alaye fun Ile ẹjọ pe lẹhin ti Alao fọ ilẹkun ẹnu-ọna ile na wọle tan ni o ba gbe maṣini olọwọ kan pẹlu awọn aṣọ lilọ ti Ọ g b ẹ n i Adeyinka Odutuga.

Iye gbogbo ẹru ti Alao ji ko ninu Ile na jẹ adọrin pọnun (£70).

Bi ọlọpa ti sọ bayi tan ni Alao ba dori kodo ninu apoti ti osi bu sẹrin.

Ni adajọ ba bere lọwọ rẹ wipe, njẹ otitọ ni ẹsun ti awọn ọlọpa fi kan ọ yi?

Alao si da lonun wipe lootọ ni ọrọ ti awọn ọlọpa sọ

Adajọ bere lọwọ Alao wipe kinni idi rẹ t' o fi lọ fọ ile onile ti o si tun ji wọn lẹru ko?

Alao ni iṣẹ ọwọ on ni on nṣe nitoripe on ko ni iṣẹ miran lati ṣe ti o ju lọ.

Ni Adajọ ba sọ fun wipe o jẹ iyalẹnu lati leri iru ọmọde iru tirẹ ti o di ogidi Ọlọ so ti nsi nfọ ile onile kakiri ilu.

Otun fi kun wipe ko yẹ ki iru awọn ọmọde bẹ ma ba awọn enia gbe larin ilu.

Ni o ba da ẹwọn ọdọ mẹrin fun pẹlu iṣẹ aṣe kara.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIOUS (Jan.21-Feb 19) Ba awọn ẹlẹgbẹ rẹ sọrọ to dara ni owuro, nṣe ni gbogbo wọn ma suru mọ ọ lati gbọ ohun ti o fẹ wi.

PISCES (Feb.20-March20) Din awọn ọja ti o nra fi sowo ku, nitori ki awọn ohun ti o nlepa r ẹ le tẹ ọ lọwọ

ARIES (Mar.21-Aprii.20) Ọjọ oni dara fun ohun kan ti o ngbero lati ṣe tabi bi o ba kuku gbe nkan na jade loni ire ati ilọsiwaju mbẹ nibẹ.

TAURUS (Apl.21-May22) Ṣọ ra rẹ, ki o maṣe na nakuna masi ṣe ṣohun ti agbara rẹ koka.

GEMINI (May23-June21) Ero tirẹ nikan ko le to fun ọrọ awọn ẹbi rẹ, lalẹ o n i ni nwọn o g b e ọrọ na kalẹ ni sisọ.

CANCER (June22-July23) Ọrọ iwọ pẹlu awọn obi rẹ nfẹ iranlọwọ gidigidi, ki o si yara lọ san gbese kan ti o ti nilẹ fun ọjọ pipẹ.

LEO (July 24 - Aug. 23) Iwọ ko ni ṣe alaigba eebu ninu ọrọ kan ti yio delẹ, ṣugbọn iwọ yio gba ẹbẹ lati ọdọ enikan wa.

VIRGO (Aug. 24 - Sept. 23) Iṣẹ ti o nṣe lojojumọ yio jẹki ara rọ ọ bẹ, ṣugbọn nkan iyanu ti iwọ ko ro tẹlẹ yio yọ si ọ ki orun to wọ.

LIBRA (Sept. 24 – Oct. 22) Rere ni gbogbo ọjọ oni lio jẹ fun ọ.

SCORPIO (Oct. 23 – Nov. 22) Ọna kan ti o fẹ gba ti o nro lọkan dara, iwọ yio ri ṣe ṣe bi o ba tọ ọna na.

SAGITTARIUS (Nov. 23 – Dec. 22) Ọrọ kekere kan yio da ija silẹ, ipari ija na yio jeki o ni ọrẹ pupọ.

CAPRICORN (Dec 23 – Jan. 20) Bi o ba nfe ilọsiwaju ninu iṣẹ rẹ, o ni lati fi ẹsẹ kun, ki o gba nihin ki o si gba lọhun.


**Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara!**

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu ko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Egbogi "Ikọ" ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibiti oti joko si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹn bere fun egbogi wọnyi:

**"Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi 'Linituss'**

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ Igbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna-ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati oru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri.

O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

**Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?**

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
Ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA", Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe
"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA
t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin'

**"WAS SALAM"**

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo [illegible] oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*
MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan

**BI O BA NI**
**Iwe—Titẹ**
*FUN*
**Lilo nibi iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**
*ATI*
**'gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO *PỌKU* NI A *SI NBGA*
IROHIN KO TO AFOJUBA
*Danwa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*

# Ẹgbẹ Amuludun ṣe isin idagbere fun Alufa Salawudeen

EKO:— Ẹnu kọ Irohin ni isin akanṣe nla ti ẹgbẹ Amuludun ṣe lati fi ṣe idagbere fun alufa Salawudeen ti on lọ si irin ajo Mecca ati Medina, ni opopo nọmba 1, Kosọkọ ni alẹ ọjọ Ọjọ bọ ti ṣe ọjọ kerindinlọgbọn oṣu yi.

Alufa Salawudeen ni alufa ti ma kọ wasi pataki ti ẹsin Islam sinu iwe Irohin Imọlẹ Iọṣẹọṣẹ lati ilu Omupo o si tun jẹ alufa akọmọ ni kewu ni Magaranta ti A n s a r u d e e n ni ilu Omupo.

Ni dede agogo mẹsan alẹ yi ni ẹ s ẹ awọn ero ti pe ṣ ọ ṣ ọ si bi Isin adura yi t'ọkunrin ati obinrin awọn ọmọde ti o duro ko jẹ ki amọ awọn ti o wa woran.

Were ni ẹsẹ awọn alufa jakanjakan nti pejọ tawọn ati awọn ọmọ kewu wọn bẹni awọn sanmari onisowo nla ati awọn gbajumọ ọkunrin ti o wa lati b iyi fun ipade na.

Bi wọn ti so ẹrọ gbohungbohun ti nwọn yio fi mọ ṣọlọ ni awọn ọmọ kewu ti bẹrẹ fa a Madiu ti wọn si kọ waka ti oba ode mu. Alfa A. B. Bakre olohun iyọ ṣe adura akoko lati fi si Isin na ose adura na a fun iṣeju mewa gbako lai fi ọkan pe meji.

Bi alufa yi ti pari adura rẹ ni alufa Yusufu Asuramu bẹrẹ sise waka ti osi tun fa a Madiu, lẹsẹlẹsẹ ti gbogbo enia si gbe lẹsẹlẹsẹ.

Lẹhin Waka ati Madiu yi ni Alufa Oseni Oro ṣe wasi kukuru diẹ fun awọn jamina lori idi rẹ ti awọn Imale nfi lọ si Mecca ati Medina.

Gbogbo ọrọ ti alufa yi sọ si awọn yungba ina a gbogbo ero ti o pejọ laje ọjọ na.

Lẹhin eyi ni Alufa Oseni wa ṣe ikilọ nla fun Alufa Salawudeen, wipe ohun ti o ba lọ si Mecca ati Medina ni ki o kọju si.

O si ṣe adura pe ki Ọlọrun sọ ọ lọ ki osi tun sọ pada ni Alufa.

Nko le salai sọ bi isin na ṣe waye ni alẹ ọjọ yi, nitope ẹniti o ba wa de ibẹ lo le fẹnu sọ iru ọpọlọpọ ohun ti o ṣẹlẹ.

Irohin fi ye wa wipe awọn ẹgbẹ Amuludun eyiti Alufa Salawudeen jẹ ọkan ninu rẹ ni o ṣe oku fa isin idagbere ha.

Awọn ẹgbẹ na se gudugudu meje ti wọn si tu se yaya a mẹfa nipa ọnati wọn fi da owo ẹbun fun alufa Salawudeen.

Owo ti gbogbo ẹgbẹ na fi silẹ jẹpọnun marun s i l e marun (£5 : 5/-) lẹhin rẹ ni awọn pataki pataki rinu ẹgbẹ na tun da owo sile marun marun gẹgẹ bi afi kun.

Nko le salai sọ diẹ ninu awọn ti ofi ẹbun silẹ fun alufa Salawudeen ni ọjọ na awọn ni Alufa Jimọh Giwa ẹgbẹ Amuludun oda pọnun kan sile (£1 1/-) alufa Lawal Ajegunlẹ pọun kan sile kan £1 1/-) Jimọh Ayinla pọnun kan sile kan (£1 1/-) ati alufa Gbadamosi owo pọnun kan sile kan ati ẹgbẹ ọrẹ mẹta.

Awọn gbajumọ wọn yi ni nwọn da owo sile mẹwa abọ mẹwa abọ lati fi k n idawo na a.

Awọn ni Alufa Salawu Oba, Abudu Kadiri alfa Kelani, Yesufu Ọba alufa Lawal Ajegunlẹ, awọn Ebi Olomu alufa Lawal Asuogbolu ati Saidi pẹlu Giwa ẹgbẹ Amuludun awọn Ẹgbẹ ọrẹ marun ati alufa Mahamadu Irapa.

A ko le ma darukọ gbogbo awọn gbajumọ lọkunrin ati lobinrin ti o da owo sile marun marun kun idawo la le ọjọ na, ṣugbọn diẹ ti ale darukọ ni wọnyi, Alufa Jimọh Akulapo, J i m ọ h Ọdẹ, Bello Amao, Amuda, Baber, Amuda Tello, Iyaafin Abibatu, Onire ati Arẹre, Oloyede Obaloyan, Ajagbe alufa. Audu, Baber, Yesufu Ajagbe ati alufa Bello.

Ọpọlọpọ miran lose itọrẹ ti o ba oju mu ni alẹ ọjọ na Ki isin idagbere na to pari ni dede ago kan abọ oru, ni alufa Salawudeen pe t o ba pada bo ki o ma ṣe pa iwa rẹ da si eyiti o ti hun tẹlẹ nitoripe orire ati mukiba rẹ ti Ọlọrun fi ta lọrẹ ni gbogbo enia nfi fẹran rẹ nibi kibi.

Awọn ohun pataki tio mu inu gbogbo awọn enia dun lalẹ ọjọ yi wipe awọn ẹbi ile Asuramu pẹlu ile ẹlẹmọ nta kangban si awọn ara ile Ajinịe tiṣe idile Alufa Salawudeen lati le fi han pe ti nwọn ni Alufa Salawudeen, bi wọn ti fi ẹnu sọ bẹni wọn nfi ọwọ sọ.

Ṣugbọn lati pa a gbogbo ọrọ na mọlẹ ẹniti ojẹ ọkan ninu awọn aṣiwaju idile ile Ajinịe nilu Eko fi owo pọunkan palẹ ọrọ na mọ.

# Igbimọ Atunto Ẹgbẹ Imọlẹ Aye

GẸGẸBI a ti fi aṣẹ fun mi lati ọdọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe, nwọn ti tu ẹgbẹ Imọlẹ Aiye tẹlẹ ka, a si ti tun da omiran silẹ ni torina ti o ba ri pe o fẹ jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ ti tun yi ki o kọwe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ọjọ kọkanla oṣu kẹrin (11/4/64) ni dede agogo mẹta ọsan.

Ẹgbẹ yi yatọ si ti atẹhinwa a si tun ti ni ofin titun miran, Eyi ni ni awọn ere ti ẹgbẹ titun na yio ma ṣe.

1. Lati maa kọ awọn ọdọ ilẹ yi ni ọna bi a ti nkọ irohin, itan, ọrọ sinu iwe Irohin lati ọdọ awọn Ọjọgbọn oniwe Irohin.
2. Ere bi Bọọlu alafẹsẹ gba, Table Tennis, Swimming, Entertainment, Ayo, Iṣẹ, Draft Ludo Picnic ati ọpọlọpọ awọn nkan miran ti ọo ma a gbọ ni [illegible]

Nitorina ti o ba fẹ tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ titun yi ki o wa si ipade ni ọjọ 11/4/64 ni nọmba 16, Bamgboṣe St., Lagos, Ao si tun yan awọn alaṣẹ ẹgbẹ titun.

Eyi ni orukọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ:—

1. J. Ọla. Okunlọla
2. Latifu Babalọla
3. Sedu Olupo
4. Abudulahi Awẹlẹnjẹ
5. Timothy Akins

Ẹ jọwọ, ẹ tete de ipade o.


# AKARA TU S'EPO!

## Iwe Itumọ Ala tun de





Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pelu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

Iye Owo:— Igo kan 5/
Dọsini 36/-

J. O. SHOYINKA
N2/99 Shittu Street
Ibadan

# IROHIN IMOLE

MOLE ORE AIYE, TENI GIOGBO LAWA

No. 568 WEDNESDAY APRIL 1, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe me'ej.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imole Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun n... (19..) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16. BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS

# AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ ALAKUKỌ FARAKỌRIN

IBADAN:— Gbogbo ile lokunṣọṣọ ti ẹṣẹ ko si gba ero fun ogunlọgọ ọkẹaimọye enia ti nwọn wa si ile ẹjọ kekere kan nigbati awọn ọlọpa mu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ fun ẹsun pe, nwọn ṣe ipade ode gbangba eyiti o le da rogbodiyan silẹ larin ilu ti o si tun le ba alafia awọn ara ilu jẹ ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu ti o kọja yi.

Ọlọpa ti o ba awọn enia mọkandinlogun na ṣẹjọ ṣe alaye fun Ile ẹjọ pe, awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ na ṣe ipade gbangba ode, ni adugbo Makọla ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu kẹta ọdun yi.

Ọlọpa na ni, nibiti nwọn ti nṣe ipade na, gbogbo wọn nkigbe lohun rara wipe "Akintola Ole, Fani Kayọde Ole" nibiti nwọn gbe nṣe ipade.

Ọlọpa na ni, nigbati on ri awọn enia na, ti nwọn nkọrin ọtẹ ati owe, ni on ba tun ri obinrin kan, Belawu Ayọka pẹlu igo ọti, ogogoro lọwọ rẹ, bi o ti ngmu ọti, ni o nta gẹẹ-gẹẹ.

Ọlọpa na tun ṣe alaye pe bi on ti mu obinrin na, ni o ba ju igo ọti ogogoro ọwọ rẹ sinu gọta, igo ọti na si fọ patapata.

Nigbati Ọlọpa na ti ro gbogbo ẹjọ rẹ tan, ni Oloye A. M. F. Agbaje ti iṣe agbẹjọro awọn Ọmọ ẹgbẹ na wa kesi Ile-ẹjọ wipe awọn enia na ko ni ẹjọ lati ro ni kotu.

Ṣugbọn Adajọ Agba Ile ẹjọ kekere na, Ọgbẹni A. Odunsi, sọ fun Ile-ẹjọ pe awọn enia na ni ẹjọ lati ro nitoripe nwọn ti rekọja ofin ti o sọ wipe, "ẹnikẹni ko gbọdọ ṣe ipade gbangba-Ode"

Adajọ na ni awọn Olujẹja na gbodọ wa sọ ti ẹnu wọn fun Ile-ẹjọ gbọ, paapajulọ Iyaafin Belawa Ayọka, ti o fọ igo Ọti Ogogoro, eyiti awọn Ọlọpa fẹ fi han ile ẹjọ.

Lẹhin eyi ni adajọ wa yẹ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ Ẹti (Ọtunla) ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi.

Oniwe irohin wa Ejongboro yio lo si Ibadan ni ọla, bi nwọn ba ti pari ẹjọ na si, ẹ o ma a gbọ o.


## Gbanjo! Gbanjo! Gbanjo!!

Eyi ni lati kede fun gbogbo awọn ONIBARA wa jake jado agbaiye pe ao bẹrẹsi ma a ta Ọja gbanjo wa fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gẹgẹbi iṣe wa lọdọọdun Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbanjo yi ni pe, iwe ti, o nti ọdọ awọn ONIBARA wa wa lati:-

**Ghana, Abijan, Cotonou, Lome ati Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tetebẹrẹ GBANJO na.

TETE WA RA TIRẸ LONI

ỌJA GBANJO NA BẸRẸ LATI 28th MAC.–30th APR

Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/- di 22/6d
Iwe Ilana Ifa, Iyanrin titẹ Etutu ṣiṣe 21/- di 18/-
Iwe Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Iṣẹgun Ajẹ 4/6d di 3/-
Iwe Ala Nla 7/6d di 5/6d
Iwe Ala ati Iwadi Nkan 2/6- di 2/-
Turari Iṣẹgun Ajẹ 10/6 di 8/-
Certificate of Appreticeship 7/6d di 5/-
Tailor's Measurement Book 7/6d di 5/6d
Iwe Itan Ala 2/6d di 1/-
Iwe Itumọ Ami Ara 4/6d di 3/-



AKIYESI:— Ẹnikẹni ti o ba ra nnu awọn ọja yi yio fi ba TURARI IṢẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa

**Shoyinka**

N2/99 Shittu Street
Ibadan

BERE OJULOWO EGBOGI:—

## Congrevds' Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọru tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikotọ eje lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati lorisirisi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni in nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

## mmoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orisirisi rọbirọki egbogi ti wọn nko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu iko iba, orerẹ lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi dango ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọr ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ila-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbog aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orisirisi omira pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Pone:h Nigeria, (Ọja Ita Faj)



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) P. O. Box Bariga (1/4/64)